GO PLACES
IN A
HILLMAN
FORM
ARAB BROS
MOTORS LTD.

IROHIN IMOLE
MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

FUN IWE TITE
Bi L e t t e r Headings, Invoices, Indents, Invitations, Posters, Tickets, Certificate fun awọn ẹkọ-ṣẹ, Circulars, Receipts, ati awọn orisirisi n k a n miran ti o ba fe te.
Bi o ba si tun ni awọn iwe ti o ti darugbo, a le so di titun fun e bakanna.
Wa si Shop:-
ODUNSUNLE PRINTING WORKS
30, Palm Church Street,
Lagos, Nigeria

VOL. V No. 201 MONDAY JUNE 26 — JULY 2 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Awon Olosa gbe jamba Miran de nwon fi Ore suni ni sise

AGBỌ Irohin pe awọn ẹgbẹ Ọlọṣa a ma ba ara wọn ṣe ipade, ọgbọn jamba ti nwọn si gbe de. ni akoko yi, jẹ eyiti yio kọ enia ni iwa ọdaju ati aladanu.

Ọkunrin kan ti nwọn npe ni J. G Williams ti o nṣiṣẹ ninu ile iṣẹ Barclays B a n k ti o ngbe opopo, Obanta, ni Apapa, ni a gbọ pe awọn Ọlọṣa da lọna pẹlu ọmọ binrin kan ti o njẹ Bogess ti o ngbe Ikoyi.

Ọlọṣa na sọ fun Williams pe ki o ko gbogbo owo ọwọ rẹ wa bi ẹni pe on lo ba wọn ṣiṣẹ rẹ.

Nwọn ri ṣile meje gba lọwọ obinrin na ṣugbọn niti on, nṣe ni on ba wọn wọ iya ija, nwọn lu ti ẹlọta si on na lara, On na si lu bansa Bẹ na ni awọn ọlọsa yi se ni i b i t i nwọn npe ni (Kuramọ waters Victoria Island Lagos) I b i ssere Omi Kuramọ ni eti Okun ni Eko Ọkunrin k a n t i o njẹ S. E Maline ti o wa ni ile Ikọsọ ni Yaba wa gba atẹgun leti Okun ni Ọlọsa yi ba wa ba ti on ti a d a pla kan lọwọ rẹ, o ni e wo lọ se, ko gbogbo o h u n ti o wa ni ọwọ rẹ wa, o ni ẹmi rẹ ni o ju owo rẹ lọ ni?

Abi owo rẹ lo ju ẹmi rẹ lọ? Ọlọsa na gbe ọwu otutu ti iye owo rẹ jẹ poun mẹtalsabọ ago isomọwọ kan ti owo rẹ jẹ poun meje abọ (£7:10) Kalamu kọwe kan ti o jẹ poun kan awo ifi soju kan ti owo rẹ jẹ poun mẹta-abọ (£3:10) ati iwe Amerika to se inu ria kiri owo rẹ jẹ meji-abọ (2/6).



## Awon agbagba ile Naijiria tio lo ko bi a ti se nsun Owo wa na

Awọn Agbagba ilẹ Naijiria ti a nwo ninu aworan yi, lo rin irin ajo lọ kakiri ilẹ awọn Oyinbo, lati soju si bi enia ti le sun Owo na, ki o ma ṣe da gbese. Nwọn ya aworan yi nigbati nwọn wa ri ile Rosia, awọn na le wa ni iduro wọnyi:— Malam Samoa Dipcharima lo duro ni ẹgbẹ ọtun, Nikita Krucheve Ọgbẹni Krucheve paapa lo d u r o ni arin aworan yi, Oloye Okotie-Eboh lo duro ti o fi aṣọ bora.

Oloye Okotie-Eboh sọ fun Ọgbẹni Nikita Krucheve wipe, nitiwa ni Ilu wa, idẹra ati alafia ni a w a fọ ni patski, ki a fi Ọla fun ẹniti Ọla nṣe tirẹ ki a si bọwọ fun ẹniti ọwọ to si.

Bi nwọn ba kuro ni Ilu Rọsia, nwọn o tun ma tẹ siwaju ninu irin ajo wọn. Iye awọn ti o rin irin ajo na ni a nwo ninu aworan yi, Oloye Okotie-Eboh ni asiwaju wọn.

# Ajegboro dagba Nki Nyin O!

MO KI GBOGBO Ẹnyin Onkawe Irohin Imolẹ kakiri Agbaiye. mo si tun ki Olotu na ẹ ku iṣẹ o, ẹ ku owuro, ẹ o jire bi? Olọrun kowa pẹlu mi, ẹ ba mi ṣe amin. Mo tun de, emi ariku ma sa, emi ọmọ gbeje, gbejọ. emi ni a ri jẹ ninu ijọgbọn, ọkunrin Olọrun, ẹniti Oluwa ko pa, ẹda kan ko le pa, mo de si ẹnyin amu gbo.

HA! ẸNYIN ARA EKO? Ẹ GBA KẸ FI MỌ TI

Gbogbo ẹniti o ba de ilu Eko, boya o wọ mọto ni tabi o wọ kọ oju omi ni yiọ mọ pe otitọ ni ọrọ mi yi, ọrọ mi ti ọsẹ yi yio jẹ lori awọn a mu gbo, bi enia ba de itẹ ku igboro ni ọna Ajẹlẹ, ṣe ni awọn enia nlo i g b o (India hep) bi ẹni lo ewe ibẹpẹ.

Bi enia ba de ibẹ ni osan, ẹ o ba wọn nibiti wọn ti nwe igbo na, wọn ko fi bo rara, gbogbo alejo ti o ba ka ninnu iwe irohin ojojumọ bi awọn Ọlọpa tiṣe wahala lati pana iru iwa a nmu igbo ni Naijiria, ko ṣe gbọ leti lati wa ri wipe ni Olu ilu Naijiria, Eko ni aṣa na gbe gbilẹ ti o si ota kiri bi isu ti a gbin.

Emi Ajẹgboro dagba fi ọwọ kesi awọn Ọlọpa Naijiria ki nwọn mu ṣe jẹki o rẹ nwọn lati tun bọ bani pana iwa buruku yi. iwa ti ko fun ilu wa ni o r u k ọ rere a fi orukọ buruku, itiju ni yio fun awa enia ilẹ Naijiria bi alejo kan ba rin kakiri ilu Eko ti o si ri pe wọn mu igbo. Sugbọn iyalẹnu ni yio jẹ bi alejo kan kan ba rin ti o si ri pe gbogb wọn lo ni ibẹru ofin ni ọkan Sugbọn ni Eko wa ni gbogbo iwa yi pin si, iyẹn ko yẹ Orilẹ ede ti o ti gbo minira lati ma ri po awọn enia inu rẹ rufin, ẹtẹ awo ni ẹtẹ ọgbẹri, gbogbo Orilẹ-ede Afirika ni o nwo Naijiria bi aṣiwaju wọn. Bẹni ita gbalasa ti Kaposi (Campos Sq.) bi enia ba fẹ jẹun nibẹ ni alẹ orun igbo koni jẹki o gbadun, ti o jẹ pe ni ọjọ kan bi mo ti de ibẹ n ọjọ na ebi ti pa mi oju mi ti ran bi oju ole bi mo ti joko ti iya ọlọka si fun mi lọka tan bi mo ti ni ki bẹrẹsi jẹun, orun igbo ko jẹki le jẹun mọ nisa ni mo binu dide, ẹnyin Onkawe mi, ẹ ma bu mi wipe mo ndakajẹ o, emi ko ni iyawo ni.

Ọrọ keji ti o mu mi kọ akọle oke iwe yi ni pe ni adugbo ti mo wi lẹkan bi enia ba de ibiti mo wi yi yio ri pe TẸTẸ tita ti ba nwọn jẹ, o ti di aṣa tabi ere wọn, ọpọlọpọ ni o ti nri iwowo nitori tẹtẹ yi, nigbati o ba fi gbogbo owo ta tẹtẹ ti ko si jẹ yio kukn wa fi ẹwu rẹ ta ko tun ni jẹ, gbogbo rẹ yio wa pari sẹri ija, iru iwa bayi ko le fun Orilẹ ede wa ni alafia ati Ominira ti o yanju, iṣẹ ẹnikan wa ni lati ma ran ara lọwọ ki ilu wa le leke, D i r a fi t i fi fi ta tẹtẹ ko dara, ẹ jẹ ka ran awọn Ọlọpa lọwọ lori iwa buruku wọnyi, o to akoko lati ma wa ire fun ilẹ wa lọna kanoa.

Mo kesi OLOFOFO, PẸTẸPẸTẸ, AYILỌKA S. Shomuyiwa, Ọgbẹni Afọlabi Olabintan ile ti ẹkọ giga University ti Ibadan, Mo bẹ yin, ẹ jẹ ka panu pọ lati ba awọn enia Naijiria sọrọ Otitọ ti o le mu wọn jawọ kuro ninu awọn iwa buruku ti o kun ode oni.
Mo fẹ esi lati ọdọ ẹnikankan yin. A O PADE LAYỌ.

# IWE SI OLOTU

IDAHUN SI ỌRỌ OLOYE G. ADEMỌLA OGUNNIYI (OFFA)

Lati Ọwọ:- S. A. ỌMỌ BALẸ

Olotu/ Gba mi laye lati sọ si ọrọ Ọgbẹni G. A. Ogunniyi ti o jade ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ 12th oṣu June 1961 ni oju ewe keji. Mo ki Ọgbẹni na pupọ fun ọrọ na ti o sọ, mo si fẹ ki o ṣe gafara fun mi. Mo fẹ fi ye ọgbẹni na wipe "Bi Ọlọgbọn ba sọro, lẹnu Omugọ ni a o ti gbọ, ki emi to le gba wipe ẹgbẹ N. P. C. lo le mu idẹra wa fun wa nilẹ Igbomina, Ọffa, ati E k i t i, mo fẹ ṣe abere ọrọ wọnyi lọdọ Ọgbẹni na ki o fi ye mi. Bi mo ba ri esi na pe o ba ọlọgbọn mu, o si ba ti lakaye dọgba, ngo ka ọrọ rẹ si ọrọ ọlọgbọn. (1) Enia melo ni gbogbo awọn oṣiṣẹ ti o mbẹ labẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin ati pe melo ni awọn ọmọ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti ti o mbẹ ninu wọn? (2) Kini anfani ti Ijọba Ibilẹ Ilorin ṣe si ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti lati ọjọ ti nwọn ti mbẹ labẹ N. P. C. ti a le ri toka si? (3) Ogunniyi fi nye wa pe, apapọ awọn enia ti o mbẹ ni agbegbe O s h u n jẹ 852, 984, sugbọn apapọ awọn enia o mbẹ ni Igbomina, Offa ati Ekiti jẹ 78,398. Njẹ a ko ha to ni ti o l e da duro funra rẹ nibi, tabi bawo ni enia ti le pọ to ki ofin to gba oluwa rẹ laye laye lati daduro fun ra rẹ? (4) Ọgbẹni na sọ wipe bi a ba ni lati duro fun ara wa, nibo ni a o ti ri owo lo. tabi Odẹkunlẹ fẹ ki a di eru owo ori ru awọn enia nibi? Idahun ti mo le fun nidi yi ni pe Kini Ijọba Ibilẹ ṣe fun idagbasoke ilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti lati igbati a ti nsan sile meji abọ ni owo ori titi di oni ri a nsan Pọun meji ati sisi, ni ipinlẹ Ariwa. Ko ha nṣe nitori idagbasoke yi ni nwọn ṣe fi kun owo na ni ndan? Mo nfẹ idahun ibere mi yi lẹsẹsẹ nitori ohun to ba ru ni loju, o ye ki a bere. O si dami loju pe iwọ Ọgbẹni Ogunniyi ẹni akọkọ ti kofẹ idagbasoke ilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti, a koiti ri ọmọ Ọffa kan ti o tapa si idaduro ilẹ wa, ninu eyi la o fi mọ ọmọ ọkọ ati ale. Ki Ogunniyi maṣe rope mo mbu on rara, ọrọ ko ri bẹ. Emi ọmọ a jẹ Balẹ ma ba lu jẹ, Ọmọ AROWORỌWỌN. Odigbo ṣe.

Olotu, iwọ yio ko ere oko dele o.

IJAFARA ŁEWU

## Ma tan Ara re je mo!

Bi o ba daju wipe "IKỌ" tabi amodi "IGBAAIYA" lo nyọ ọ lẹnu ti ọjọ rẹ si pẹ pupọ, ma tan Ara rẹ jẹ mọ nipa rira awọn "EGBOGI RỌBIRỌBI" ti nwọn nta kakiri Ode nisinsinyin owo pọku. Wọn ko le ṣe iwosan "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ rara Ṣọbu kan na ti o le ri oriṣiriṣi egbogi "IKỌ" ti o daju, atamatase ati Ajẹbidan lati ilu awọn Jamani, Faranse, ati Itali (Tatanbulu) ra ni Igboro Ilu Eko tabi ni ṣọbu awọn ara Ilu Saro ti nwọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22858 Nigeria (Oja ita Faji)**




Oja ko ta, ema Polowo oja yin sinu iwe Irohin Imole K' e si ma ka ıi Osese

